

# ATỌNÀ ÌSỌDÒFIN-ABẸLÉ

## Àdéhùn Maputo – Abala 14

## NÀÌJÍRÍÀ

MEWC
Make Every Woman Count

SOLIDARITY FOR AFRICAN WOMEN'S RIGHTS
A force for freedom

MOUVEMENT DE SOLIDARITÉ POUR LES DROITS DES FEMMES AFRICAINES
Une force pour la liberté

BAOBAB
FOR WOMEN'S HUMAN RIGHTS

AKINA MAMA WA AFRIKA

# ATỌ́NÀ ÌSỌDÒFIN-ABẸ́LÉ

## Àdéhùn Maputo – Abala 14

## NÀÌJÍRÍÀ

Produced and Published by Make Every Woman Count
Email: info@mewc.org  Website: www.mewc.org

Copyright © 2026

Design and Layout: James Chunguli, Crimson Communications Ltd.

All rights reserved. Redistribution of the material presented in this work is encouraged by the publisher, provided the original text is not altered, that the original source is properly and fully acknowledged and that the objective of redistribution is not for commercial gain. Please contact the publisher if you wish to reproduce, redistribute or transmit, in any form or by any means, this work or any portion thereof.

# Ìfáárà

Àfikún Àdéhùn sí Àlàkalẹ̀-Àdéhùn Afíríkà lórí Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn àti tAráàlú lórí Ẹ̀tọ́ àwọn Obìnrin ní Afíríkà, tí gbogbo ayé mọ̀ sí Àdéhùn Maputo, dúró gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn irin-iṣẹ́ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn onítẹ̀síwájú jùlọ ní àgbáyé. Àjọ Àpapọ̀ Afíríkà gbà á wọlé ní ọdún 2003. Ó ṣàgbékalẹ̀ àfojúsùn onígboyà fún iyì, ìdọ́gba, àti òmìnira-lórí-ara-ẹni àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin kárí àpapọ̀-ilẹ̀-ńlá náà. Fún ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ àwọn obìnrin tí ó ń gbìyànjú láti dáàbò bò, Àdéhùn náà kọjá ìwé-òfin kan lásán. Ìlérí ni.

Atọ́nà yìí wáyé **láti ọwọ́ Make Every Woman Count (MEWC)** àti **Solidarity for African Women's Rights Coalition (SOAWR)**. Ó pèsè ọ̀nà àmúlò gidi látinú àdéhùn àgbáńlá-ayé àti ti ẹlẹ́kùnjẹkùn sí ti òtítọ́ orílẹ̀-èdè nípa fífi ẹsẹ̀ àwọn àmúyẹ Àdéhùn náà múlẹ̀ ní àyíká ajẹmọ́- òfin, ìṣèlú, àti àṣà-àwùjọ ti orílẹ̀-èdè yìí ní pàtó.

## *Ìdí tí Àdéhùn Maputo fi Ṣe Pàtàkì*

Ní ààrin gbùngbùn atọ́nà yìí ni méjì nínú àwọn àlàkalẹ̀ Àdéhùn náà tí ó ṣe kókó jùlọ wà: Abala 5 pe àwọn orílẹ̀-èdè láti fòpin sí àwọn àṣà apanilára bí dídá/gígé abẹ́ obìnrin (FGM/C), ìgbéyàwó ọmọdé, àti àwọn àṣà mìíràn tó ń dúnkookò mọ́ ìlera àti iyì àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin; nígbà tí Abala 14 ṣe ìdánilójú fún àwọn ẹ̀tọ́ ìlera ìbísí àwọn obìnrin, pẹ̀lú àǹfàní sí ìfètòsọ́mọbíbí, ìtọ́jú aláìléwu fún aláboyún, àti oyún-ṣíṣẹ́ lọ́nà-ẹ̀tọ́ ní àwọn ìgbà tí ìjanilógun ìbálòpọ̀, ìfipábánilòpọ̀, ìlájọṣepọ̀-ẹ̀jẹ̀-kan-náà bá wáyé, tàbí nígbà tí oyún bá ń mú ewu bá ìlera ọpọlọ tàbí ara obìnrin.

Abala wọ̀nyí yanjú díẹ̀ lára àwọn ìdúnkookò tí ó tóbi jù tí àwọn obìnrin ń kojú: ikú aláboyún tó ṣe é dènà, oyún-síṣẹ́ aláìláàbò, ìwà-ipá ajẹmọ́-abo, àti àwọn àṣà apanilára tó ń dènà kí àwọn obìnrin láṣẹ lórí ara wọn. Àdéhùn náà kò ṣàgbékalẹ̀ ọ̀ràn wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àánú tàbí àríyànjiyàn ajẹmọ́-ìwà ọmọlúàbí, ṣùgbọ́n ó rí wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn tí a lè fi àṣẹ òfin gbé ró.

## *Lílóye Ìsọdòfin-Abẹ́lé*

Ìgbà tí Àdéhùn máa ń yí ìgbé-ayé padà nìkan nígbà tí àmúyẹ rẹ̀ bá dé ọ̀dọ̀ àwọn tí ó ń dáàbò bò. *Ìsọdòfin*-abẹ́lé *jẹ́ ìgbésẹ̀ síso àwọn ojúṣe-àdéhùn àjẹmájọ-àgbáyé di ọ̀fin, ìlànà, àti ìṣe* orílẹ̀-èdè kí *ẹ̀tọ́ lè di ohun tí ó ṣe é* gbé ró ní àwọn ilé-ẹjọ́ abẹ́lé àti nípasẹ̀ àwọn iṣẹ́ ìjọba ojoojúmọ́. Bí èyí ṣe ń wáyé dúró lórí ètò ìdájọ́ orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan.

Ní àwọn orílẹ̀-èdè **a-kan-**òfin-**pọ̀-mọ́-**àdéhùn-àgbáyé **(monist states)**, àwọn àdéhùn tí wọ́n bá fọwọ́ sí máa ń di mímúlò tààrà, wọn a sì máa jẹ gàba lórí òfin abẹ́lé orílẹ̀-èdè. Síbẹ̀ ní mímúlò gidi, àwọn ilé-ẹjọ́ àti àjọ ìjọba lábẹ́lé kì í sábà lo àwọn àmúyẹ yìí, èyí ń fi àlàfo sílẹ̀ láàrin àgbékalẹ̀-èrò (tíọ́rì) àti àmulò rẹ̀ gan-an (reality).

Ní àwọn orílẹ̀-èdè a-ya-òfin-sọ́tọ̀-sí-àdéhùn-àgbáyé (dualist states) àdéhùn kì í di òfin nípasẹ̀ ìfọwọ́sí nìkan. Wọ́n nílò àkànṣe ìgbésẹ̀ Ilé-ìgbìmọ̀ Aṣòfin láti sọ wọ́n dòfin, àti láti gbé wọn ró. Títí ìyẹn yóò fi wáyé, àwọn ìlérí Àdéhùn náà wà bí àníyàn lásán ni.

Nínú etò méjèèjì, ìsọdòfin-abẹ́lé ni afárá ààrin ẹ̀jẹ́-àdéhùn àti ìrírí mímúṣẹ rẹ̀ láwùjọ. Dídí àlàfo yẹn ni ìdí pàtàkì fún atọ́nà yìí.

MEWC Make Every Woman Count



SOLIDARITY FOR AFRICAN WOMEN'S RIGHTS A force for freedom MOUVEMENT DE SOLIDARITÉ POUR LES DROITS DES FEMMES AFRICAINES Une force pour la liberté

# I. Èrèdí Atọ́nà Yìí àti Bí a ó Ṣe Lò ó

Atọ́nà ìsọdòfin-abẹ́lé yìí jẹ́ ohun-èlò àmúṣiṣẹ́ tí a pinnu fún àwọn akópa àjọ ajàfẹ́tọ̀ọ́ àwùjọ, àwọn aṣòfin, àti àwọn agbẹjọ́rò tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ láti mú ìtẹ̀síwájú bá ìsọdòfin- abẹ́lé Àdéhùn Maputo ní Nàìjíríà. Àfikún Àdéhùn sí Àlàkalẹ̀-Àdéhùn Afíríkà lórí Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn àti tAráàlú lórí Ẹ̀tọ́ àwọn Obìnrin ní Afíríkà (Ìwé Àdéhùn Maputo), tí Nàìjíríà fọwọ́ sí ní ọjọ́ 16 oṣù-kejìlá ọdún 2024, jẹ́ irin-iṣẹ́ ẹ̀tọ ọmọnìyàn àgbáyé kan tí Àjọ-àpapọ̀ orílè-èdè Afirika (AU) ṣàgbékalẹ̀ láti 'ri dájú pé ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin di gbígbélárugẹ, mímúṣẹ, àti dídáàbòbò láti jẹ́ kí wọ́n gbádun gbogbo ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn wọn ní kíkún.'[i]

Àdéhùn náà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ orí-ọ̀rọ̀-aṣekókó lórí àwọn ẹ̀ka ẹ̀tọ́:[ii]

| Orí-ọ̀rọ̀-aṣekókó Àwọn Ẹ̀ka Ẹ̀tọ́ | Abala |
|---|---|
| Àwọn Ẹ̀tọ́ Ọrọ̀-ajé & Ìgbáyégbádùn Àwùjọ | 13 & 19 (c) |
| Àwọn Ẹ̀tọ́ Ajẹmọ́ igbéyàwó (pẹ̀lú Ìgbéyàwó Ọmọdé) | 6 |
| Àwọn Ẹ̀tọ́ Ìlera & Ìbímọ/ìbísí | 14 |
| Ààbò kúrò lọ́wọ́ Ìwà-ipá (pẹ̀lú Abẹ Dídá/Gígé fún Obìnrin) | 3, 4 & 5 |
| Ẹ̀tọ́ láti Kópa nínú Ìgbésẹ̀ Ètò-Ìṣèlú & Ìpinnu-Ṣíṣe | 9 |
| Ẹ̀tọ́ sí Ìfọ̀kànbalẹ̀/Àlàáfíà & Ààbò kúrò lọ́wọ́ Ìjà Ẹgbégun | 10 & 11 |
| Àwọn Obìnrin tó ní Ààbò Àrà-ọ̀tọ̀ | 20, 21, 22, 23 & 24 |

Nàìjíríà ti fọwọ́ sí Ìwé Àdéhùn Maputo láìfi iyèméjì kankan sí i, ṣùgbọn ìpèníjà ṣì wà nípa ìmúlò rẹ̀ lórí ìfiyàjẹ-abo lákòókò ìrọbí, ìtọ́jú aláboyún pẹ̀lú ọ̀wọ̀, àti ìtọ́jú pàjáwìrì lákòókò ìrọbí. A nílò ìpolongo àti àtúnṣe sí i lórí Abala 14 tí ó fẹsẹ̀ ẹ̀tọ́ obìnrin sí ìlera, pẹ̀lú ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ìbísí múlẹ̀.[iii]

Atọ́nà yìí gbájú mọ́ híhun ìpolongo ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ ati ìbísí gẹ́gẹ́ bí ìlera ìyálọ́mọ àti ìdílé, ó sì ṣàgbékalẹ̀ àwọn àwíjàre ẹrọ fún sísàtúnṣe àwọn òfin ìbílẹ̀ láti mú wọn ṣe wẹ́kú pẹ̀lú Àdéhùn Maputo láti dáàbò bo àìláṣẹ-ìfọwọ́kan-ara- àti ààbò ara-ẹni àwọn obìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà. Atọ́nà náà gbájú mọ́ àwọn ète àti àpẹẹrẹ àgbéyẹ̀wò fún àwọn àjọ ajàfẹ́tọ̀ọ́ àwùjọ, àwọn ajàfẹ́tọ̀ọ́, àti àwọn oníṣẹ́-òfin afọnrere-ẹ̀tọ́. Fún ìsọdòfin-abẹ́lé tó yanrantí, àwọn ẹgbẹ́ wọ̀nyí gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ papọ̀.

# II. Àyíká-Ìṣèlẹ̀ Orílẹ̀-èdè àti Ìlànà Òfin

Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà gba òmìnira láti ọwọ́ Orílẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ́sì ní ọjọ́ 1 0sù 10 odún 1960.[iv] Pẹ̀lú iye èèyàn tó ju mílíọ̀nù 237.5 lọ, ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orílẹ̀-èdè tí èèyàn pọ̀ sí jùlọ ní àgbáyé.[v] Nàìjíríà ní ìpele ìjọba méta: ìpele ìjọba-àpapọ̀, Ìjọba Ìpínlẹ̀ 36, àti àwọn Ìjọba Alákoso Ìbílẹ̀ 774.[vi] Nàìjíríà jẹ́ orílẹ̀-èdè Olófin-Ìjọba Àwaarawa tí Ààrẹ ń darí, ó ní Ìgbìmọ̀-Aṣòfin àdìbòyàn tí Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Àpapọ̀ gbé kalẹ̀, àti Ẹ̀ka Ìdájọ́ olómìnira. Onímbejì ni Ìgbìmọ̀-Aṣòfin náà, tí ó ní Ìgbìmọ̀-Aṣòfin Àgbà (Senate) àti Ilé Ìgbìmọ̀-Aṣojúṣòfin (House of Representative).[vii]

Nàìjíríà jẹ́ orílẹ̀-èdè a-ya-òfin-sọ́tọ̀-sí-àdéhùn-àgbáyé (dualist state), èyí túmọ̀ sí pé Àdéhùn Maputo kò di òfin tàárà nípa fífọwọ́sí. Láti ni ipa tó lóòrìn ní Nàìjíríà, àwọn abala Àdéhùn náà gbọ́dọ̀ di gbígbéwọ inú ìhun òfin abẹ́lé nípasẹ̀ ìgbésẹ̀ kan tí wọ́n ń pè ní ìsọdòfin-abẹ́lé. Àwọn òfin àgbáyé tí a ti sọ dòfin abẹ́lé nìkan ló ṣe é gbé ró.[viii] Títí tí Àdéhùn Maputo yóò fi di òfin abẹ́lé, àwọn ẹ̀jẹ́-àdéhùn pàtàkì rẹ̀ fún òmìnira lórí ara ẹni àwọn obìnrin àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn wà gẹ́gẹ́ bí èròǹgbà lásán ni.

Onírúnrú ọ̀nà ni a lè fi sọ Àdéhùn náà di òfin abẹ́lé:

- Gbogbo Àdéhùn náà lódindi ni ìbò ìdá méjì-nínú-mẹ́ta Ilé Ìgbìmọ̀-Aṣòfin lè sọ dòfin.
- A lè tọ́ka sí Àdéhùn náà nígbà tí a bá ń ṣe àkọsílẹ̀ òfin.
- A lè lo Àdéhùn náà gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ-ìpìlẹ̀ fún òfin síṣe.

## *Ìpìlẹ̀ Òfin fún Àwọn Ẹ̀tọ́ Ìbímọ/Ìbísí*

Ìwé-Òfin Ìjọba Àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ọdún 1999 pèsè ìpìlẹ̀ ìlànà-òfin lórí èyí tí èèyàn fi lè béèrè fún àwọn ẹ̀tọ́ ìbímọ/ìbísí.[ix] Orí IV ṣe ìfẹsẹ̀múlẹ̀ àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn gbòògì, pẹ̀lú ẹ̀tọ́ sí ìwàláàyè. (Abala 33), iyì ọmọnìyàn (Abala 34), òmìnira ara-ẹni (Abala 35), àṣírí ara-ẹni (Abala 37) àti òmìnira kúrò lọ́wọ́ ìdẹ́yẹsí (Abala 42). Àwọn ìpèsè yìí ní í ṣe tààrà pẹ̀lú bíbéèrè ẹ̀tọ́ nípa òmìnira lórí ara-ẹni, ìlera ìbísí, àti ìtúsílẹ̀ lọ́wọ́ ìfiyàjẹ-aboyún lákòókò ìrọbí.

Ní pàtàkì, Abala 34 kàn án nípá fún ìjọba láti sètò ìdáàbòbò fún ìpamọ́ àti ààbò ẹnìkọ̀ọ̀kan. Èyí ṣe é fẹ̀ lójú láti mú ìdánilójú wà fún òmìnira lórí ara ẹni àti ààbò ara awọn obìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà – nípa sísètò ìpamọ́ àti ààbò àwọn obìnrin lọ́nà tó ní í ṣe pẹ̀lú mímú àdínkù bá ìwà-ipá adálórí-lákọ-lábo, abẹ dídá/gígé fábo, ìdẹ́yẹsí adálórí-lákọ-lábo, àti ikú ajẹmọ́-ìrọbí.

Àmọ́, a gbọ́dọ̀ gbà pé ìkánilọ́wọ́kò alágbára kan wà: Nígbà tí Orí II Ìwé-òfin náà darí ìjọba láti pèsè ohun-èlò ètò-ìlera, àṣẹ wọ̀nyí kò ṣe é gbé ró lábẹ́ òfin ilé-ẹjọ́. Èyí túmọ̀ sí pé ará-ìlú kò kàn lè pe ìjọba lẹ́jọ́ torí pé wọ́n kùnà láti pèsè wọn.[x] Ìṣe àìṣeégbéró àwọn òfin ẹ̀tọ́ ìlera nílé-ẹjọ́ mú àdínkù bá àwọn ọ̀nà tó wà fún kíkó ìjọba ní pápá mọ́ra láti dáhùn fún ìkùnà nínú ìtọ́jú aboyún/onírọbí àti ìbísí. Ní pipe ẹjọ́-òfin eléte-àfojúsùn, a gbọ́dọ̀ farabalẹ̀ hun ẹjọ́ yípo àwọn ẹ̀tọ́ aṣeégbéró nílé-ẹjọ́ èyí tí ó wà ní Orí IV dípò àwọn ìlànà ìdarí tó wà ní Orí II.

## *Ìlànà-Ìhun Òfin Ọ̀ràn-Dídá*

Nàìjíríà ń ṣàmúlò ètò òfin ọ̀ràn-dídá oníbejì, pẹ̀lú àtubọ̀tán tààrà fún òmìnira ìbímọ/ìbísí. Ní Gúúsù Nàìjíríà, Ìwé òfin Ìwà-ọ̀daràn díwọ̀n irúfẹ́ nǹkan tí ẹnikẹ́ni lè yàn láti ṣe lórí ìbímọ/ìbísí, nípa àgbékalẹ̀ ìjìyà ẹ̀wọ̀n tí ó tó ọdún 14 fún ẹni tí ó bá sètò oyún-ṣíṣẹ́, àyàfi tí ó bá jẹ́ láti fi gba ẹ̀mí obìnrin náà là.[xi] Ní Àríwá Nàìjíríà, Ìwé-òfin Ìjìyà lábẹ́ òfin bákan náà pe oyún-ṣíṣẹ́ ní ìwà-ọ̀daràn pẹ̀lú ìjìyà ẹ̀wọ̀n ńlá-ńlá; Láfikún, àwọn ìpínlẹ̀ àríwá 12 ń ṣàmúlò ilé-ẹjọ́ Sharia ní fẹ̀gbẹ́kgbẹ́ pẹ̀lú Ìwé-òfin Ìjìyà ìjọba-àpapọ̀, pẹ̀lú fífi ìpele ìdíwọ̀n kan kún un.[xii] Àwọn àlàkalẹ̀ méjèèji yìí yàtọ̀ síra nínú àgbékalẹ̀ wọn ní pàtó: Ìwé òfin Ìwà-ọ̀daràn kò kọ àyàfi láti gba-ẹ̀mí-iyá-là sílẹ̀ kedere, bó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹjọ́ *Rex tako Edgar* àti *Rex tako Bourne* ṣàgbékalẹ̀ àtọ́kasí *àpẹẹrẹ-ò*fin tí ó fàyè gba oyún-ṣíṣẹ́ lákòókò irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀,[xiii] *ṣugbọ́n méjèèji* kéré jọjọ sí ìpìlẹ̀ tí a nílò lábẹ́ Abala 14(2)(c) ti Àdéhùn Maputo.

## *Àlàkalẹ̀-òfin Aṣekókó*

Ní àfikún sí *Àdéhùn Maputo, oríṣiríṣi òfin abẹ́lé* ló *ń* darí àlàkalẹ̀ òfin fún ìlera àti ẹ̀tọ́ ajẹmọ́-*ìbálòpọ̀ àti ìbímọ/ìbísí:*

- *Òfin (Ìdènà) Ìwà-ipá sí Ènìyàn* **tọdún 2015 (Òfin VAPP)** sọ ìfipábánilòpọ̀, *ìwà-ipá nínú ilé, àti abẹ́ dídá/gígé fún abo (FGM/C)* di ìwà-ọ̀daràn. Amọ́, agbègbè Olú Ìlú *Ìjọba-àpapọ̀* (FCT) nìkan ni Òfin VAPP ti múlẹ̀. Kí ó tó le ṣiṣẹ́ ní àwọn Ìpínlẹ̀ 36 Nàìjíríà, ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ sọ ọ́ dòfin ab*ẹ́lé*.[xiv]
- *Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọdé* **ọdún 2003** fi gbèdéke lé ọjọ́-orí tó kéré jùlọ *fún ìgbéyàwó sí ọdún 18* ó sì fòfin de ìbọ́mọdéláj*ọ*ṣepọ̀. Gẹ́gẹ́ bí i ti *Òfin VAPP, Ó nílò ìsọdòfin-ab*ẹ́*lé* ti ìpele *ìpínlẹ̀ kó tó lè ṣiṣẹ́ ní àwọn agbègbè tí kò sí lábẹ́ Olú Ìlú ìjọba-àpapọ̀* (FCT).[xv]
- *Òfin Ìlera Ìjọba-Àpapọ̀ ọdún* **2024** pèsè *àlà*kalẹ̀ fún *ìdàgbàsókè àti ìsàkóso ètò ìlera ìjọba-àpapọ̀,* nipa kíkànnípá àwọn iṣẹ́ etò-ìlera tí ó ṣe pàtàki pẹ̀lú ìlera ìbímọ/ìbísí àti ìtọ́jú ajẹmọ́-ìrọbí, t*í ó sì nílò àwọn irin*-isẹ́ ètò-ìlera l*á*ti pèsè ìtọ́jú pàjáwìrì láìnáání ipá *láti sanwó*.[xvi]
- *Òfin Ìdójútòfò Ìlera Ìjọba-àpapọ̀* **ti ọdún 2022** (tí ó rọ́pò Òfin NHIS ọdún 1999) pèsè àlàkalẹ̀ fún ìdójútòfò ìlera ọlọ́wọ́ja-káríayé, pẹ̀lú ọwọ́jà l*órí iṣẹ́-ìlera ìbísí àti ajẹmọ́-ìrọbí*.[xvii]

# III. Ipò Ìsọdòfin-abẹ́lé

## *Ìtẹ̀síwájú látìgbà Ìfọwọ́sí-Àdéhùn*

Nàìjíríà ti gbé ìgbésẹ̀ láti mú ìgbéga bá àìlàṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti ààbò ara-ẹni nípa gbígbé díẹ̀ lára àwọn Àdéhùn Maputo wọ inú òfin abẹ́lé, pẹ̀lú Ìlànà-òfin Ìdọ́gba-Takọtabo tí wọ́n gbà wọlé ní ọdún 2015.[xviii] Àmọ́, ìlò rẹ̀ sì ń ṣe ṣégeṣège. A ṣì nílò akitiyan sí i láti mú òfin abẹ́lé wà ní ìbámu pẹ̀lú Àdéhùn náà.

Abala 3, 4, àti 5 Àdéhùn Maputo pe àwọn orílẹ̀-èdè láti dáàbò bo àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin kúrò lọ́wọ́ ìwà-ipá. Ọ̀kan nínú mẹ́ta àwọn obìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà ni yóò ní ìrírí ìkọlù ìwà-ipá ajẹmọ́-ara tàbí ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ ni ọjọ́-ayé wọn.[xix] Ní ọdún 2015, Nàìjíríà fòǹtẹ̀ lu Òfin VAPP, èyí tó fojú sun àtidènà ìwà-ipá nínú ìgbé-ayé ẹnìkọ̀ọ̀kan àti ní àwùjọ, tó sì pèsè ìrànwọ́ fún àwọn amóríbọ́ nínú ìjanilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ìwà-ipá abẹ́-ilé.[xx] Òfin yìí di fífòǹtẹ̀lù lẹ́yìn ìpolongo alágbára ọlọ́dún 14.[xxi] Ó ṣeni láàánú pé, wọn kò mu un lò lọ́nà tó já geere kárí gbogbo ìpínlẹ̀, kùdìẹ̀kudiẹ ṣì wà nínú bí wọ́n ṣe ń pèsè ìrànwọ́ fún àwọn afarakáásá ìwà-ipá. 19 nínú ìpínlẹ̀ 36 nìkan ló tí ì ṣàgbékalẹ̀ àwọn Ibi-iṣẹ́ Ìgbọ̀rọ̀dùn Ìjanilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ láti pèsè ìrànlọ́wọ́ àti ìtọ́ni fún àwọn afarakáásá.[xxii]

Abala 5 Àdéhùn Maputo ní pàtakì wúlò fún Nàìjíríà bí ó ti fòfin de FGM/C. Mílíọ̀nù 9.9 amoríbọ́ nínú FGM/C ló ń gbé ní Nàìjíríà, èyí ni iye amóríbọ́ tó pọ̀ jù ní àgbáyé.[xxiii] Nàìjíríà ti yanjú FGM nínú Òfin VAPP àti nínú Ìlànà Ètò-Ìlera Ìjọba-àpapọ̀ rẹ̀,[xxiv] ó sì ṣe àgbàwọlé Ìlànà Àpapọ̀ & Ètò Ìmúṣẹ́ṣe àdáwà fún Ìparẹ́ Abẹ́ Dídá/Gígé fún Obìnrin (2021-2025).[xxv] Abala 6 Àdéhùn Maputo pè fún ìfòpinsí ìgbéyàwó ọmọdé. Ní ọdún 2016, Nàìjíríà ṣe àgbàwọlé Ète Ìjọba-Àpapọ̀ láti mú Àdínkù bá Ìgbéyàwó Ọmọdé.[xxvi] Ṣùgbọ́n, a ṣì nílò ìyànjú si láti ṣètò ààbò lòdì sí FGM/C, ìgbéyàwó ọmọdé àti ìfipágbéniníyàwó, àti ìwà-ipá ajẹmọ́-ara. A tún gbọ́dọ̀ ro bí àwọn nǹkan yìí yóò ṣe nípa lórí àwọn ọ̀dọ́ Nàìjíríà tí ó máa tiraka pẹ̀lú lílàṣẹ lórí ara ẹni àti ìwà-ipá ní àsìkò ètò-ìmọ̀-ẹ̀rọ yìí.

Abala 9 Àdéhùn Maputo pè fún àwọn obìnrin láti kópa sí i nínú ìṣèlú àti ìpinnu-ṣíṣe. Ìlànà-òfin Ìdọ́gba-Takọtabo Àpapọ̀ Nàìjíríà 'ṣètò fún ìdá 35% ó-kéré-tán fún ìkópa àwọn obìnrin nínú òṣèlú yálà àfisípò tàbí àfibòyànsípò.'[xxvii] Àmọ́, Nàìjíríà wà lára àwọn tí ìkópa obìnrin nínú òṣèlú rẹ̀ kéré jùlọ ní àgbáyé

pẹ̀lú ìda 5% ìjókòó péré tó jẹ́ ti obìrin ní Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Àpapọ̀.[xxviii] Láti yanjú èyí, Àbá-òfin Ìjókòó Àrà-ọ̀tọ̀ fún àwọn Obìnrin yóò ṣẹ̀dá àwọn ìjókòó pàtó fún àwọn obìnrin.[xxix] Sísojú ajẹmọ́-ìṣèlú yìí ṣe pàtàkì púpọ̀ torí pé àwọn obìnrin ní ipò aṣáájú ti ṣagbátẹrù àwọn àtúnṣe tí ìlú nílò gidi lórí òfin ètò-ìlera àti ààbò.[xxx] Síṣàfikún sí iye àwọn obìnrin ní Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ìdánilójú àmúlò gbogbo abala Àdéhùn Maputo.

## Àwọn Kùdìẹ̀kudiẹ̀ àti Ìdènà

Nítorí pé Nàìjíríà kò tíì sọ Àdéhùn Maputo di òfin-abẹ́lé ní kíkún, kùdìẹ̀kudiẹ̀ wà láàrin àwọn kókó-ète Àdéhùn náà àti àmúlò wọn, òfin abẹ́lé àti ìrírí ìgbé-ayé àwọn obìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà. Fífọwọ́sí Àdéhùn náà jẹ́ ìgbésẹ̀ kan pàtàkì nínú gbígbà àti jíjẹ́jẹ̀ẹ́ láti dáàbò bo ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin. Àmọ́, ẹ̀jẹ́-àdéhùn yìí kò farahàn ní kíkún nínú àwọn òfin abẹ́lé, ìlànà, àti àwọn iṣẹ́-ìtọ́jú ètò-ìlera.

### Àwọn Kùdìẹ̀kudiẹ̀ àti Ìdènà Ajẹmófin àti Ìlànà: Oyún-ṣíṣẹ́ àti Ìtọ́jú Ajẹmọ́-ìrọbí

Nàìjíríà ní ìdá iye ikú aláboyún/ajẹmọ́-ìrọbí tó ga gan-an,[xxxi] èyí rí bẹ́ẹ̀ lápá kan nítorí ìwà-ipá ìfiyàjẹ-aboyún lákòókò ìrọbí àti àìní ètò ìtọ́jú pàjáwìrì ní àkókò ìrọbí. Láti mú àdínkù bá iye ikú ajẹmọ́-ìrọbí, orílẹ̀-èdè náà ti ṣàmúlò Àlàkalẹ̀ Ète fún Ìfòpinsí Àìsàn-egbò Ìrọbí ní Nàìjíríà.[xxxii] Àmọ́, a ṣì nílò iṣẹ́ si láti dènà ìfiyàjẹ-aboyún lákòókò ìrọbí kí á sì ri dájú pé ìtọ́jú aboyún àti ìtọ́jú ajẹmọ́-ìrọbí aláìléwu ń wáyé lásìkò.

Kùdìẹ̀kudiẹ̀ ajẹmófin tó lágbára jù dá lórí níní àǹfàní sí oyún-ṣíṣẹ́. Àìdọ́gba híhànde kan wà láàrin àwọn òfin abẹ́lé Nàìjíríà àti àwọn ẹ̀jẹ́-àdéhùn rẹ̀ lábẹ́ Abala 14(2)(c) Àdéhùn Maputo, tí ó pè fún àwọn ìpínlẹ̀ láti fàyè gba oyún-ṣíṣẹ́ nígbà tí ìṣẹ̀lẹ̀ ìjannilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀, ìfipábánilòpọ̀, àti ìbálòpọ̀-ẹ̀jẹ̀-kan-náà bá wáyé àti ìgbà tí oyún bá ń fa ewu tó lágbára fún ìlera ọpọlọ àti ara obìnrin. Yálà Ìwé-òfin Ìwà-ọ̀daràn (tí wọ́n ń lò ní Gúúsù Nàìjíríà) tàbí Ìwé-òfin Ìjìyà (tí wọ́n ń lò ní Àríwá Nàìjíríà), kò sí èyí tó tọ́ka sí àwọn ìpìlẹ̀ ìfẹ̀lójú wọ̀nyí: méjèèjì ló pààlà sí bíbófinmu oyún-ṣíṣẹ́ pé kò gbọdọ̀ kọjá àsìkò tí ó bá pọn dandan, ìyẹn láti fi gba ẹ̀mí obìnrin là, pẹ̀lú ìjìyà-òfin tó wúwo - tó tó ẹ̀wọn ọdún 14 – fún obìnrin àti àwọn òṣìṣẹ́ elétò-ìlera tí wọ́n bá ṣe kọjá àyè kékeré yìí. Èyí fi àwọn òfin Nàìjíríà sí ara àwọn tó ní ààlà jù ní ẹkùn náà tí ó sì tako àwọn ẹ̀jẹ́ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn rẹ̀ ní tààrà-tààrá.

Àwọn ààlà yìí kò fi gbogbo ara ṣíṣẹ́ láti dènà oyún-ṣíṣẹ́. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ọ̀kan nínú oyún méje ló ń yọrí sí ṣíṣẹ́,[xxxiii] bẹ́ẹ̀ ni 63% oyún-ṣíṣẹ́ ló léwu, tí wọ́n ń dá kún 10% iye ikú aboyún/ajẹmọ́-ìrọbí.[xxxiv] Bí ó tilẹ̀ yé ọ̀pọ̀ aṣòfin pé oyún-ṣíṣẹ́ tí ó léwu ń fa ikú aboyún/ajẹmọ́-ìrọbí, díẹ̀ nínú àwọn aṣòfin ló ní ọkàn láti sọ̀rọ̀ ta ko àwọn òfin oyún-ṣíṣẹ́ tó wà nílẹ̀ torí àbùkù ajẹmáṣà-àwùjọ àti ẹ̀sìn.

Àlàfo àgbékalẹ̀ kan tún mú àwọn ìṣòro náà díjú si. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Nàìjíríà fọwọ́ sí Àdéhùn Maputo ní oṣù-kẹwàá ọdún 2004 láìpààlà, wọn kò tíì sọ ọ́ di òfin abẹ́lé orílẹ̀-èdè gẹ́gẹ́ bí Ìpín 12 Ìwé-òfin ṣe sọ. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn àlàkalẹ̀ Àdéhùn náà, pẹ̀lú Abala 14, kò ṣe é gbé ró tààrà ní àwọn ilé-ẹjọ́ ilẹ̀ Nàìjíríà.[xxxv] Àlàfo tí ó wà láàrin Àlàkàlẹ̀-òfin Ìjọba-àpapọ̀ àti àmúlò ní ìpele-ìpínlẹ̀ ṣe kókó bákan náà: àwon àgbékalẹ̀ ètò-ìlera onítẹ̀síwájú tí wọ́n gbà wọlé ní ìpele Ìjọba-àpapọ̀ – pẹ̀lú Òfin VAPP àti Òfin àwọn Ẹ̀tọ́ Ọmọdé – kò di mímúlò tààrà bẹ́ẹ̀ ní àwọn ìpínlẹ̀ 36 ti Nàìjíríà. Nítorí ètò-ìlera wà lórí àtẹ-òfin aláfọwọ́sowọ́pọ̀ṣe (láàrin ìjọba àpapọ̀ àti ìpínlẹ̀), àwọn afọnrere-ẹ̀tọ́ gbọ́dọ̀ ṣe àseeṣetúnṣe gbogbo ìyànjú wọn ní gbogbo ilé ìgbìmọ̀-aṣòfin ìpínlẹ̀ láti mú kí wọ́n gbà á wọlé kí wọ́n sì ya owó sọ́tọ̀ fún un, láti ṣẹ̀dá àlàkalẹ̀ tó pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ nínú èyí tí ààbò ajẹmófin àwọn obìnrin ti lè yàtọ̀ gidi, ó dúró lórí agbègbè ibi tí ó bá wà.

### *Àyípadà Tuntun Ajẹmọ́-Ilé-ẹjọ́*

Láìnáání àlàkalẹ̀ akóninípápámọ́ra yìí, ọdún 2025 mú ìdájọ́ aláyìípadà kan wá pẹ̀lú ipa nlá lórí ọgbọ́n ìjàfẹ́tọ̀ọ́. Nínú ẹjọ́ *Reproductive Justice Initiative Foundation (RJIF) tako Alákoso Ètò Ìdájọ́ Orílẹ̀-èdè & Àwọn yòókù*, Ilé-ẹjọ́ Gíga Ìjọba-Apapọ̀ ní Abuja dájọ́ pé fífi ipá mú afarakáásá ìwà-ipá ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ láti gbé oyún títí di ọjọ́ ìkúnlẹ̀ tẹ ẹ̀tọ́ asekókó wọn sí ìlera ajẹmọ́-ara àti ọpọlọ lójú.[xxxvi] Ìpinnu yìí dúró gẹ́gẹ́ bí ìtẹ́wọ́gbà àkọ́kọ́ látọ̀dọ̀ ilé-ẹjọ́ abẹ́lé pé ìtọ́jú ìlera ajẹmọ́-ìbísí fún àwọn amóríbọ́ afarakáásá ìwà-ipá ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ jẹ́ ẹ̀tọ́ aṣekókó ọmọnìyàn, kì í ṣe ìwà ọ̀daràn. Àwọn amòfin àti àwọn akópa ẹgbẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́-àwùjọ nílò láti lo ìdájọ́ yìí bí ìpìlẹ̀ fún ìgbésẹ̀ ìtẹ̀síwájú ẹjọ́ àti gẹ́gẹ́ bí irin-iṣẹ́ alagbára fún ìyípadà ìjíròrò ṣíṣe-òfin.

### *Kùdìẹ̀kudiẹ àti Ìdènà Ajẹmọ́-Àṣà-àwùjọ àti -Ẹ̀sìn*

Láti so Àdéhùn Maputo dòfin abẹ́lé ní kíkún tàbí láti tẹ̀síwájú nípasẹ̀ ilé-àṣòfin, a nílò ìdá méjì-nínú-méta àwọn ọmọ Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Àpapọ̀. Lọ́wọ́lọ́wọ́, kò dájú pé Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Àpapọ̀ yóò fọ̀ntẹ̀ lu òfin láti yanjú ìpèníjà wọ̀nyí, torí kò sí ìpìnnu ìṣèlú bẹ́ẹ̀ ni wọ́n kùnà láti fi ìtọ́jú ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti -ìbísí sí ipò àkọ́kọ́.[xxxvii]

Bí ó bá dọ̀rọ̀ yíyan ìlànà-òfin, ọ̀pọ̀ ọmọ ilẹ̀ Nàìjíríà ni ìrònú ẹ̀sìn máa ń darí. Ẹ̀sìn ti wọ inú òṣèlú púpọ̀ ní Nàìjíríà, debí pé àwọn àjọ ẹlẹ́sin àti àwọn olórí àṣà ń kó ipa pàtàkì nínú dídarí ìjíròrò àwùjọ àti ìpinnu àlàkalẹ̀-ètò ìjọba.[xxxviii] Èyí ti mú àbùkù bá ìlò èròjà ìfètòsọ́mọbíbí àti àwọn ẹ̀tọ́ ìbísí.[xxxix] Ìyànjú láti fẹ àǹfàní rírí àwọn èròjà ìfètòsọ́mọbíbí lójú tàbí kí wọ́n dáàbò bo ìlera ajẹmọ́-ìbalòpọ̀ ń kojú àtakò.[xl] Oyún-ṣíṣẹ́, ní pàtàkì, jẹ́ ohun tí wọ́n korò ojú sí, bẹ́ẹ̀ ni ìyànjú láti ṣàmúlò àwọn òfin a-móyún-ṣíṣẹ́-rọrùn ló ti kojú àtakò líle àti ọ̀rọ̀ ìlòdìsí látọ̀dọ̀ àwọn àjọ 'afọnrere-ẹbí' àti 'afọnrere-ìlú/orílẹ̀-èdè'.[xli]

Àtúnṣe ìlànà ìronú (tí a sàlàyé nísàlẹ̀ yìí) ṣe pàtàkì láti mú lílò Àdéhùn náà rọrùn si ní àyíká òṣèlú onípèníjà yìí.

## IV. Àwọn Ète Ìṣagbátẹ̀ru-Ẹ̀tọ́ àti Bíbá-àwọn-aṣòfin-sọ̀rọ̀

Ọ̀nà méjì pàtàkì ló wà láti so Àdéhùn Maputo di òfin abẹ́lé ní Nàìjíríà:

1. Nípasẹ̀ àwọn àjọ alágbàwí-àwùjọ àti àwọn ajàfẹ́tọ̀ọ́, lílo òfin-ṣíṣe láti ṣàmúlò díẹ̀ tàbí gbogbo Àdéhùn náà pẹ̀lú ìfọwọ́sí ìdá méjì-nínú-méta àwọn ọmọ ilé-ìgbìmọ̀ aṣòfin.
2. Nípasẹ̀ ìṣagbátẹ̀rù-ẹ̀tọ́ pẹ̀lú ìlànà àti àtúnṣe òfin, wọ́n máa ń lo ìpenilẹ́jọ́ láti sàgbékalẹ̀ àpẹẹrẹ-òfin tó gbòòrò fún ìtọ́kasí, tí yóò ṣẹ̀dá ìlànà tuntun tí yóò sì yí ìjíròrò àwùjọ padà.

Àwọn ète yìí ní í ṣe pẹ̀lú àkójọ ìṣagbátẹ̀ru-ẹ̀tọ́ aláfojúsùn láìdáwọ́dúró, iṣẹ́ ìyípadà àwùjọ, àti ṣíṣàgbékalẹ̀ ọ̀nà ìfagbára-òsèlú ṣe ohun tó tọ́.

### *Àjọ Alágbàwí-Àwùjọ àti Àwọn Ajàfẹ́tọ̀ọ́*

Àwọn àjọ alágbàwí-àwùjọ, àwọn ẹgbẹ́ àgbègbè àti ẹgbẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́-ilú ṣe pàtàkì láti rí i dájú pé ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà di mímúṣẹ. Nígbà tí àwọn àjọ eléròngbàkannáà bá ń ṣiṣẹ́ papọ̀ lórí onírúnrú-ọ̀nà pẹ̀lú àfojúsùn kan náà, wọ́n lè borí àṣà ìtìjú, kí wọ́n sì sàgbékalẹ̀ ipá abẹ́lé àti ìfẹ́ ìfagbára-òsèlú ṣe ohun tó tọ́.

## *Àpẹẹrẹ Àgbéyẹ̀wò: Àpapọ̀-Ẹgbẹ́ Alágbawí-Ẹ̀tọ́-Àwùjọ Orílẹ̀-èdè láti Fòpin sí Ìgbéyàwó Ọmọdé ní Nàìjíríà (CSO-ECM) – Ẹ̀kọ́ Àwọn Ọmọdébinrin*

Àjọ CSO-ECM[xlii] jẹ́ àpapọ̀ àtagbà ẹgbẹ́ àwọn àjọ tí kì í ṣe tìjọba àti àwọn àjọ alágbàwí-àwùjọ tó gbájú mọ́ ìfòpinsí ìgbéyàwó ọmọdé àti ìfipágbéniníyàwó káàkiri orílẹ̀-èdè náà títí ọdún 2030. Pẹ̀lú ṣíṣe iṣẹ́ nípasẹ̀ àwọn ẹ̀ka ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ àti ti àpapọ̀, àpapọ̀-ẹgbẹ́ náà ń sètò-ìdarí ìgbèjà-ẹ̀tọ́, ìkórajọ àwọn ènìyàn láti ẹsẹ̀kùkú, àti ipa lórí ìlànà ìṣèjọba láti dáàbò bo àwọn ẹ̀tọ́ aṣekókó àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin. Kókó afojúsùn ète wọn kan lọ́wọ́lọ́wọ́ ni gbígbé ẹ̀kọ́ àwọn ọmọbìnrin sí ipò ohun-èlò akọ́kọ́ láti mú kí ṣíṣe ìgbéyàwó ọmọ pẹ́, ní fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú ìṣagbátẹrù ìsọdòfin-abẹ́lẹ̀ Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọdé (Child Rights Act) àti Ìlànà Àpapọ̀-Orílẹ̀-èdè láti Kásẹ̀ Ìgbéyàwó Ọmọdé Nílẹ̀. Nípa níní àṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn olùdarí-èrò àwùjọ, àwọn alágbàwí ọ̀dọ́, àti àwọn aya ọba àti ìjòyè, àpapọ̀-ẹgbẹ́ náà ń ṣiṣẹ́ láti wó àwọn ìgbàgbọ́ àwùjọ tó ti rinlẹ̀ palẹ̀, ṣe ìgbéǹde àwọn ìlànà ìpadàwọlé-sílé-ẹ̀kọ́ fún àwọn ọmọdébìnrin tó gboyún tàbí àwọn tó ti sègbèyàwó, àti láti ṣàgbékalẹ̀ àyíká tó ní ààbò tó sì dọ́gba fún ìran tí ń bọ̀ lẹ́yìn.

## *Àpẹẹrẹ Àgbéyẹ̀wò: Àjọ Ìgbéláruge àti Ọ̀nà Ìdáàbòbò Ẹ̀tọ́ àwọn Obìnrin (WRAPA) – Ìyípadà-Àṣà*

WRAPA[xliii] ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn adarí ìgbàgbọ́, ẹ̀sìn, àti àṣà ìbílẹ̀ láàrin ọdún 2005 àti 2017 láti yanjú ìṣòro ìṣe ẹ̀sìn àti àṣà tó ń fa ìgbéyàwó ọmọdé ní àwọn agbègbè apá ìwọ̀-oorùn àríwá Nàìjíríà. Lápapọ̀, àwọn alákòóso wọ̀nyí ṣàgbékalẹ̀ Hútúbà kan, ìyẹn àkójọpọ̀ àwọn wáàsí Ànábì kan, tí ó jádìí àwọn irọ́ tí ó ń dá kún ìgbéyàwó ọmọdé àti ìfipágbéniníyàwó. Lẹ́yìn náà ni wọ́n tú Hútúbà náà sí àwọn èdè ìbílẹ̀, tí àwọn olórí àṣà sì lò ó. Àpapọ̀ mọ́ṣálááṣí 105 ló ṣamúlò Hútúbà yìí lákòókò àdúà ìrun Jímọ̀. Nípa fífọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn adarí ẹ̀sin láti yí àwọn ìṣe ajẹmáṣà padà, WRAPA ti tún ní àǹfàní láti nípa lórí àwọn ìlànà ìjọba àti àtúnṣe ajẹmọ́-òfin.

## *Àpẹẹrẹ Àgbéyẹ̀wò: Ìpolongo Lòdì sí Oyún Àìtọ́jọ́ (CAUP) – Ìmọ̀-Pípín*

Láti ọgbọ̀n ọdún sẹ́yìn, Àjọ CAUP[xliv] ti ń ṣagbátẹrù ìpolongo fún àtúnṣe òfin oyún-ṣíṣẹ́ ní Nàìjíríà. Ó ti fikùnlukùn pẹ̀lú àwọn ìgbìmọ̀ olóòtú gbogbo àwọn ìwé-ìròyìn pàtàkì àti àwọn ajábọ̀-ìròyìn nípa àwọn àyọrísí oyún-ṣíṣẹ́ aláìláàbò. Ó ti ṣe àwọn àpérò ìta-gbangba ńlá-ńlá àti àwọn ètò ajẹmọ́-ẹ̀kọ́, pẹ̀lú àwọn àpéjọ-ìdánilẹ́kọ̀ọ́ agbègbè lórí ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin. Ó ti ṣàgbékalẹ̀ Ẹgbẹ́ Agbégbèésẹ̀ fún Ìlera Ọ̀dọ́langba, èyí tí ó ti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ iṣẹ́-ìṣègùn lórí ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ìbísí. CAUP tún ti ṣẹ̀dá ìlànà ìtọ́nisọ́nà Ìlapa-ẹ̀kọ́/Kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù lórí ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti àwọn ẹ̀tọ́ ìbísí fún Ilé-Ẹ̀kọ́ Iṣẹ́-Ìṣègùn Ilẹ̀ Nàìjíríà. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé akitiyan rẹ̀ kò tíì ní àṣeyọrí láti mú àtúnṣe bá àwọn òfin oyún-ṣíṣẹ́ orílẹ̀-èdè náà, ìpolongo ọlọ́dún mẹ́wàá rẹ̀ ń fi ìpìlẹ̀-iṣẹ́ lélẹ̀ fún òfin-ṣíṣe láti ṣe bẹ́ẹ̀ ní Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Àpapọ̀.

## *Àwọn Ọgbọ́n Àmúlò*

- Ẹ pèsè àǹfàní fún pínpín-ìmọ̀ nípa síṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn oníròyìn; àwọn àjọ-abẹ́lé; àwọn oníṣẹ́ ìṣègùn; àwọn adarí ẹ̀sìn àti àṣà; àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ẹ̀ka-òfin, bí àwọn adájọ́, àwọn olùpẹ̀jọ́-ìjọba, àti àwọn abánipẹjọ́.
- Ẹ ri dájú pé àkóyawọ́ wà nípa títọpinpin àti mímójútó èyíkéyìí ìwà ìtẹ̀tọ́-ẹni-lójú-mọ́lẹ̀/ìfiyàjẹni-lọ́nà-àìtọ́ láwùjọ.

- Ẹ mú àwọn tó wà nípò àṣẹ-ìjọba kó àkóyawọ́ nípa ṣíṣètò ìpolongo gbangba láti bẹnu-àtẹ́ lu àìláfọkànsìn tàbí àìnítẹ̀síwájú ìjọba, kí ẹ sì fi àwọn àkọsílẹ̀ ìròyìn-ìkọ̀kọ̀ ránṣẹ́ sí àwọn ẹgbẹ́ abojútó- ẹ̀tọ́.
- Ẹ ṣètò àtìlẹyìn àwùjọ nípa ṣíṣe iṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn adarí àwọn àgbègbè láti mú ìdàgbàsókè bá ipá wọn.
- Ẹ ṣètò àwọn ìpolongo ìjàfẹ́tọ̀ọ́ àti ìtanijí àwọn èèyàn.
- Nígbà tí ẹ bá ń ṣe àpérò àgbọ́yé pẹ̀lú àwọn aṣètò-ìlànà-ìjọba àti àwọn àjọ ìjọba, ẹ pe àwọn adarí àṣà àti ẹ̀sìn, àti àwọn adáàbòbo-ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn síbẹ̀.
- Ẹ ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn adarí òṣèlú tí wọ́n fẹ́ láti gba ọ̀ràn náà kanrí kí ẹ sì dárúkọ àwọn adarí tí ó kọ̀ láti kó àkóyawọ́.

## *Ìṣagbátẹrù àti Àtúnṣe Ajẹmọ́-Òfin*

Ìgbẹ́jọ́-abẹ́-òfin ti di ohun-èlò alágbára, tí ó ń ga si, láti dáàbò bo ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, yí òfin padà, àti láti mu kí ìjọba kó àkóyawọ́. Àwọn ilé-ẹjọ́ ń kó ipa tí ó ṣe kókó láti ri dájú pé ìjọba mú àwọn ojúṣe rẹ̀ sí àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin ṣẹ nígbà tí ìgbésẹ̀ ilé-ìgbìmọ̀-aṣòfin bá kùnà láti ṣe bẹ́ẹ̀. Ìṣagbátẹru àti àtúnṣe ajẹmọ́-òfin tí ó papọ̀ mọ́ àwọn àjọ alágbàwí-àwùjọ àti ìjàfẹ́tọ̀ọ́ aláìdáwọ́dúró lè ṣe àṣeyọrí láti mú àyípadà wá.

Lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan, àǹfàní ń wà fún ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ láti sàgbékalẹ̀ ìtọ́ka àpẹẹrẹ-òfin, kó si di ohun amáyìípadàwá fún àwùjọ àti ìlànà-ìjọba. Ọgbọ́n àmúlò yií ni wọ́n ń pè ní Ìgbẹ́jọ́-abẹ́-òfin eléte-àtúnṣe. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ àjọ alágbàwí-àwùjọ ní Nàìjíríà ti lo ìlànà òfin àgbáyé náà láti polongo fún ìyípadà, díẹ̀ nínú wọn ló tíì lo Ìgbẹ́jọ́-abẹ́-òfin eléte-àtúnṣe títí dòní.[xlvi]

## *Àpẹẹrẹ Àgbéyẹ̀wò - **Gbígbé Àpẹẹrẹ-Òfin Kalẹ̀***

Ní ọdún 2009, àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba ní Àbújá  ń hùwà-ipá ajẹmọ́-ara àti ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ sí àwọn obìnrin. Bí wọ́n ti fẹjọ́ wọn sun àwọn aláṣẹ tó, ṣe ìwà-ipá náà ń tẹ̀síwájú. Ní ọdún 2014, Dorothy Njemanze àti àwọn méta mìíràn gbé ẹjọ́ náà lọ sí Ilé-Ẹjọ́ Àwùjọ Àwọn Orílẹ̀-Èdè Ìwọ̀-Oòrùn Afiríkà (ECOWAS) – ilé-ẹjọ́ gíga àpapọ̀ àrà-ọ̀tọ̀ kan tí wọ́n fi Àdéhùn ECOWAS gbé kalẹ̀, tí kò nílò kí àwọn olùpẹ̀jọ́ kọ́kọ́ ṣàmúlò àtúnṣe ilé-ẹjọ́ abẹ́lé. Wọ́n dájọ́ náà gbe àwọn obìnrin wọ̀nyí ní ọdún 2017 nínú ẹjọ́ *Dorothy Njemanze & àwọn 3 Yòókù tako Ìjọba Àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà* (Suit No. ECW/CCJ/APP/17/14). Ilé-Ẹjọ́ náà dajọ́ pé Nàìjíríà kùnà láti dáàbò bò wọ́n lọ́wọ̀ ìdẹ́yẹsí akọ-n-bábo àti ìwà-ipá adálórí-lákọ-lábo, pẹ̀lú ẹ̀rí pé wọ́n rúfin Àdéhùn Maputo.[xlvii]

Ìgbà àkọ́kọ́ nìyí tí Àjọ Àgbáyé Abójútó-ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn kankan yóò fòfin mú orílẹ̀-èdè kan pé kò kó àkóyawọ́ lórí Àdéhùn Maputo. Ó ṣàgbékalẹ̀ àpẹẹrẹ-òfin alágbára ẹlẹ́ka-ẹkùn nípa bí a ṣe le bojú tó àwọn ẹjọ́ ìdẹ́yẹsí akọ-n-bábo àti ìwà ipá adálórí-lákọ-lábo ní ìpele ajẹmọ́-ẹkùn, Ó sì ṣàfihàn ìwúlò pàtó Ilé-Ẹjọ́ ECOWAS fún àwọn olùpẹ̀jọ́ ní Nàìjíríà: ní iyàtọ̀ sí ọ̀pọ̀ àwọn ilé-ẹjọ́ ajẹmọ́-ẹkùn àti ti àgbáyé, ó fàyè gba kí wọ́n gbé ẹjọ́ wá tààrà láìsí pé wọ́n kọ́kọ́ ti yanjú rẹ̀ tì ní ilé-ẹjọ́ abẹ́lé. Gẹ́gẹ́ bí àjọ *Alliances for Africa*, ọ̀kan lára àwọn àjọ tí ó ń ṣàtìlẹyìn ṣe kíyèsí i: 'Ó ṣe pàtaki láti ní àṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn àjọ mìíràn tí wọ́n ní ìríri ìjinlẹ̀ nínú ìgbẹ́jọ́-abẹ́-òfin eléte-àtúnṣe ju àwa fúnra-wa lọ.'[xlviii]

### *Àpẹẹrẹ Àgbéyẹ̀wò – Ìdájọ́ Abẹ́lé Ọdún 2025 lórí Oyún-Ṣíṣẹ́ fún àwọn Amóríbọ́*

Ní mímọ lé àpẹẹrẹ-òfin ajẹmọ́-ẹkùn yìí, àwọn ilé-ẹjọ́ abẹ́lé ti bẹ̀rẹ̀ sí í yi nǹkan padà. Ní Ọṣù-kẹfà ọdún 2025, nínú ẹjọ́ *RJIF tako Alákoso Ètò Ìdájọ́ Orílẹ̀-èdè*, Ilé-Ẹjọ́ Gíga Àpapọ̀ ní Àbújá dájọ́ pé fífi ipá mú pé àwọn amóríbọ́-afarakáásá ìwà-ipá ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ láti tẹ̀síwájú pẹ̀lú oyún jẹ́ títẹ ẹ̀tọ́ wọn sí ìlera ajẹmọ́-ara àti -ọpọlọ lójú lábẹ́ òfin.[xlix] Ìdájọ́ yìí ṣe pàtàkì fún ìdí méjì. Àkọ́kọ́, ó pèsè àṣẹ ìdájọ́ abẹ́lé, ní fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ àpẹẹrẹ-òfin ECOWAS, pé ètò ìlera ìbísí jẹ́ èyí tí ìwé-òfin dáàbò bò. Ìkejì, ó ṣẹ̀dá ọ̀nà kan láti ro àròjàre pé àwọn àlàkalẹ̀ akánilọ́wọ́kò Ìwé-òfin Ìwà Ọ̀daràn àti Ìwé-òfin Ìjìyà bí wọ́n ti ṣe ń lò wọ́n fún àwọn amóríbọ́-afarakáásá ìfipábálòpọ̀ àti ìjanilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀, fúnra-wọn gan-an, kò bófinmu. Àwọn Agbẹjọ́rò nílò láti rò bí wọ́ń yóò ṣe mọ lé ìpìlẹ̀ yìí nígbà tí wọ́n bá ń yan ẹjọ́ fún ìgbẹ́jọ́-òfin eléte-àtúnṣe.

## *Àpẹẹrẹ-òfin Ajẹmọ́-ẹkùn lórí Oyún-ṣíṣẹ́*

Ìgbẹ́jọ́-abẹ́-òfin eléte-àtúnṣe lè ṣiṣẹ́ dáadáa lórí ọ̀rọ̀ oyún-ṣíṣẹ́ torí pé àlàyé òfin nípa àwọn òfin tó wà nílẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ kéré. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n fòfin de oyún-ṣíṣẹ́ àfi tó bá jẹ́ láti gba ẹ̀mí ìyá là, àǹfàní kan wà láti fẹ ìtumọ̀ 'gbígba ẹ̀mí ìyá là' lójú. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé orílẹ̀-èdè Malawi ní irú òfin yìí kan náà, Àjọ Abójútófin Malawi – nípasẹ̀ ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ kan – dábàá ìfẹ̀lójú sí ìtumọ̀ 'gbígba ẹ̀mí là' pé kó ní àfikún ìdáàbòbò ìlera ọpọlọ àti ara.[l] Ìdájọ́ *RJIF* ní Nàìjíríà sílẹ̀kùn ọ̀nà àfiwé abẹ́lé kan, pàápàá fún àwọn amóríbọ́-afarakáásá ìwà-ipá ajẹmọ́-ìbálòpọ̀.

Nàìjíríà tún lè rí ìwúrí láti ara àwọn ẹkùn-àkóso-ìdájọ́ *mìíràn* bí i Ghana, Kenya, àti Rwanda níbi tí wọ́n ti fi òfin ilé-ẹjọ́ gbé oyún-ṣíṣẹ́ aláìléwu ró.[li]

## *Àwọn Ìgbésẹ̀ àti Èrò fún Ìgbẹ́jọ́-òfin Eléte-Àtúnṣe*

Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ nínú ìgbẹ́jọ́-òfin eléte-àtúnṣe ni mímọ afẹjọ́sùn tó yẹ tí ó ní àkókò àti ẹ̀jẹ́-àdéhùn láti ṣe ẹjọ́ náà. A tún gbọ́dọ̀ ṣètò owó tó tówó láti ṣàtìlẹyìn fún afẹjọ́sùn àti agbẹjọ́rò rẹ̀, pàápàá níbi tí ìgbẹ́jọ́ ti lè pẹ́. Ní àfikún, a gbọ́dọ̀ sọ fún afẹjọ́sùn ní kíkún àwọn ewu tó rọ̀ mọ́ ọn kí ó sì múra sílẹ̀ fún ìgbénisáyé àti ìwádìí fínnífínní láti ọ̀dọ̀ àwọn oníròyìn.

Ó ṣe pàtàkì láti yan ibi tí ìdájọ́ yóò ti nípa lórí ọ̀pọ̀ ẹkùn-àkóso-ìdájọ́ tí yóò sì yá láti rí gbà. Ní Nàìjíríà, ẹjọ́ lè lo àìmọye ọdún ní ilé-ẹjọ́ kí wọ́n tó dá a.

Àwọn ẹjọ́ tó ní í ṣe pẹ̀lú ìlera àti ẹ̀tọ́ ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ìbísí lè kojú àwọn àfikún ìpèníjà. Fún àpẹẹrẹ, *ìtìjú àti àbùkù àwùjọ lórí ìtọ́jú ajẹmọ́-ìṣàkóso-ìbísí lè nípa lórí* Ilé-ẹjọ́ Nàìjíríà. Ìgbàgbọ́ ajẹmẹ́sìn ẹni àwọn tí yóò ṣe ìpinnu lórí ẹjọ́ lè nípa lórí àbájáde ẹjọ́. Ní irú ìgbà báyìí, àwọn ilé-ẹjọ́ ajẹmọ́-ẹkùn tàbí ajẹmọ́-orílẹ̀-Afíríkà lè pèsè ọ̀nà mímúnádóko si fún ṣíṣe ìgbẹ́jọ́-òfin eléte-àtúnṣe.

# V. Àwọn Ọ̀nà Tuntun àti Èyí tó ń Yọjú

Àpàpọ̀-ẹgbẹ́ àwọn àjọ kan, tí àjọ BAOBAB fún Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn àwọn Obìnrin ṣetò, pẹ̀lú àtìlẹyìn Akina Mama wa Afrika nípasẹ̀ ìpèse-owó láti ọ̀dọ̀ Amplify Change, pẹ̀lú Àjọ Àpapọ̀ fún Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn; Àjọ Àpapọ̀ fún Ẹ̀kọ́ Ìṣòfin àti Ìjọba-àwaarawa; Àjọ Ìgbésẹ̀ fún Ìwádìí, Àtinúdá àti Ìgbèjà-Ẹ̀tọ́ nínú Ìdàgbàsókè; àti Ìgbìmọ̀ Àpapọ̀ Àwọn Ẹgbẹ́-òṣèlú, ti para pọ̀. Àpàpọ̀-ẹgbẹ́ yìí ń ṣe kòkárí àfojúsùn

àtinúdá ọlọ́dúnméjì kan, láti Oṣù-kẹfà ọdún 2025 sí Oṣù-kẹsàn-án ọdún 2027, láti pè fún ìyípadà òfin àti àdéhùn-òfin láti sọ Àdéhùn Maputo di ohun àrídìmú nínú ìgbé-ayé àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin ní Nàìjíríà. Àwọn ète-àmúlò àkọ́kọ́ rẹ̀ ni ìṣagbátẹrù-ẹ̀tọ́, ìkóníyànjọ àti pípín-ìmọ̀ pẹ̀lú èròngbà ìkákòóyawọ́ ajẹmọ́-òṣèlú àti ṣíṣe àmúlò Àdéhùn-Àgbáyé náà. Àpàpọ̀-ẹgbẹ́ náà ti kàn sí àwọn alákòóso pàtàkì-pàtàkì bí àwọn àjọ alábojútó àdéhùn-òfin, àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ òfin-ṣíṣe, àti àwọn adarí ẹgbẹ́-òṣèlú. Nípasẹ̀ àjọṣepọ̀ aláfojúsùn pẹ̀lú àwọn alákòóso wọ̀nyí, akitiyan rẹ̀ ní àǹfàní ìmọ̀ nípa ìsàkóso-ìjọba, àwọn àlàkalẹ̀ ajemófin, àti ìkóníyànjọ fún ìgbésẹ̀-òṣèlú.

## *Àtẹ Àtúnrọ-àlàyé Ète-Ìgbésẹ̀*

Láti ṣèrànwọ́ yíyanjú àtakò ọjọ́-pípẹ́ sí àwọn ẹ̀tọ́ ìlera ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ àti ìbísí, àpàpọ̀-ẹgbẹ́ náà ti ṣe kóríyá fún àtúnrọ-àlàyé iṣẹ́ tí ó ń rán láti lè ní ìfikùnlukùn dáadáa sí i pẹ̀lú àwọn adarí àṣà àti ẹ̀sìn àti àwọń akópa nínú òfin-ṣíṣe. Ìlànà yìí ń wá láti ṣagbátẹrù ìyípadà ajẹmọ́-ìwé-òfin àti òfin tí a nílò kíákíá, èyí tí ó le ní ipa rere lórí ìgbé-ayé àwọn obìnrin àti àwọn ọmọdébìnrin, bí a tí ń ní àkàsí àwọn òtítọ́ àyíká òṣèlú.

| Láti | Sí |
|---|---|
| Ìlàṣẹ lórí ara ẹni àti Ìjólóòótọ́ | Àìlàṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti Ààbò Ara-ẹni |
| Ìlera Ajẹmọ́-Ìbálòpọ̀ àti àwọn Ẹ̀tọ́ Ìbímọ/Ìbísí | Ìṣèyá-ọmọ Láìléwu àti Ìlera Ìdílé |
| Ìparun àwọn Àṣà Apanilára | Ìgbéró Ìjẹ́mímọ́ àti Iyì Ènìyàn |

Àtúnrọ-àlàyé yìí ṣe kókó fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí pàtàkì:

- Gbígbojú sórí Àìlàṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti Ààbò Ara-ẹni yóò pè fún lílo Ìpín 34 **Ì**wé-Òfin Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Gẹ́gẹ́ bí Ìwé-Òfin náà ti sọ, ìjọba ní àṣẹ-ojúṣe láti rí i dájú pé ààbò ẹnìkọ̀ọ̀kan fẹsẹ̀ múlẹ̀.
- Gbígbojú sórí Ìṣèyá-ọ́mọ Láìléwu àti Ìlera Ìdílé yóò darí àkíyèsí sí ikú aláboyún/ìrọbí, tí ó jẹ́ ohun tó jẹ ìjọba àpapọ̀ pẹ̀lú àwọn adárí ẹ̀sìn lógún. Èyí yóò mú àjọṣe àti ìfọwọsowọ́pọ̀ wá dípò àtakò.
- Gbígbojú sórí Ìgbéró Ìjẹ́mímọ́ àti Iyì Ènìyàn tumọ̀ sí Ìlànà-Àgbékalẹ̀ iyì ajẹmófin àti ajẹmáṣà. Yóò fàyè gba ìfọnrere-ẹ̀tọ́ àti àmúlò VAPP kárí gbogbo ìpínlẹ̀ àti ìdáàbòbo lọ́wọ́ FGM/C, Ìgbéyàwó ọmọdé àti Ìfipágbéniníyàwó, àti ìwà-ipá ajẹmọ́-ara.

## *Àwọn Ìgbésẹ̀ tó kàn àti Àbá*

Sísọ Àdéhùn Maputo dòfin Abẹ́lé ṣe kókó láti ri dájú pé àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin Nàìjíríà ní àǹfàní láti jẹ̀gbádùn àwọn ẹ̀tọ́ wọn, àìlàṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti ààbò ara-ẹni ní kíkún. Àyípadà ṣeéṣe nípasẹ̀ akitiyan alájọṣepọ̀ kárí ẹ̀ka òfin, àwùjọ, àti òṣèlú. Àwọn ìgbésẹ̀ àfisíṣe àti àbá ni a tò sí ìsàlẹ̀.

### *Fún Àwọn Aṣòfin àti Aṣetò-ìlànà-ìjọba*

- Ẹ kọ àbá-òfin kí ẹ sì gbe kalẹ̀ láti ṣàtúnṣe sí àwọn Òfin ìjìyà àti Òfin Òdaràn láti mú wọn wà ní ìbámu pẹ̀lú Abala 14(2)(c) ti Àdéhùn Maputo. Pẹ̀lú ṣíṣe àfikún àwọn àfi fún ìjanilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀, ìfipábánilòpọ̀, ìbálòpọ̀-ẹ̀jẹ̀-kan-náà, àìṣedáadáa ọlẹ̀-inú, àti ìlera ọpọlọ.

- Ẹ ró àmúlò ìlànà-ìjọba ti Ẹ̀tọ́ Lákọ-Lábo (Gender Policy) àti Òfin Àìfàyègba Ìlò Ìwà-ipá lòdì sí àwọn Ènìyàn (VAPP) lágbára, nípa rírí i dájú pé Àwọn Ibi-iṣẹ́ Ìṣètọ́jú Ìjanilógun Ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ wà láti ṣètò àtìlẹyìn àti iṣẹ́-ìtọ́jú fún àwọn afarakáásá ní gbogbo ìpínlẹ̀.
- Ẹ kojú àwọn ìpalára tó bá ń yọjú. Ẹ sètò àbá-òfin láti kojú ìpalára orí-afẹ́fẹ́ tí ó ń fa ìpalára aláìdọ́gba fún àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin, bí ìdúnkookòmọ́ni-orí-afẹ́fẹ́, ìfi-àkáálẹ̀-àwòrán orí-afẹ́fẹ́ ṣèrùbani. àpínká àwòrán ìhòòhò-ènìyàn láìfọwọ́si, àti ìhàlẹ̀mọ́ni lórí-afẹ́fẹ́.

## *Fún àwọn Agbẹjọ́rò*

- Ẹ lo ìgbẹ́jọ́-òfin eléte-àtúnṣe gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti fi àpẹẹrẹ-òfin lélẹ̀ fún àtúnṣe ìlànà-ìjọba.
- Ẹ ṣe ìfẹ̀lójú sí àwọn àfi-ìbófinmu tí wọ́n fi sí òfin oyún-ṣíṣẹ́ pẹ̀lú àfikún àwọn ewu tó rọ̀ mọ́ ìrònú-èèyàn àti ọrọ̀-ajé tó ń wu aláboyún.
- Ẹ sàmúlò Ìpín 34 Ìwé-Òfin, nípa iyì ọmọ ènìyàn, èyí tí ó ṣe ìdánilójú ààbò ara-ẹni àti ìpamọ́, sí àwíjàre nípa Àìláṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti ààbò ara-ẹni àwọn obìnrin.

## *Fún Àwọn aṣojú ẹgbẹ́-ajàfáwùjọ*

- sàgbékalẹ̀ àwọn àṣepọ̀ tó gbòòrò láti sàkóso àwọn akitiyan tó ní í ṣe pẹ̀lú ìfọwọ́sí(-òfin) pẹ̀lú àwọn alákòóso tó yẹ tó bá nífẹ̀ẹ́ láti ṣàṣepọ̀ pẹ̀lú wa, àti àwọn aṣojú ìjoba, àwọn àjọ ẹgbẹ́-ajàfáwùjọ, àwọn àjọ ẹ̀tọ́ obìnrin, àti àwọn aládàáni.
- Láti ṣàgbékalẹ̀ ìfagbára-òṣèlú ṣe ohun tó tọ́, ẹ fi ìbáṣọ̀rọ̀ àwọn ọmọ Ilé-Ìgbìmọ̀ Asòfin Àpapọ̀ àti àwọn adarí òṣèlú mìíràn ṣáájú. Ẹ kàn sí àwọn asòfin láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àjọṣepọ̀ àwọn adarí-èrò àwùjọ àti àwọn adarí ẹ̀sìn àti àwọn ọ̀dọ́. Ẹ polongo fún àfikún àwọn obìnrin asòfin, kí ẹ rí i pé Nàìjíríà dé ìpele ìdá 35% ó kere tán fún ìkópa àwọn obìnrin nínú òṣèlú tí Ìlànà-ìjọba Ẹ̀tọ́ Lákọ-Lábo gbé kalẹ̀. Ẹ ṣètò àwọn aṣòfin mìíràn láti ṣagbátẹrù ìpolongo ẹ̀tọ́ àìláṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti ààbò ara-ẹni láàrin àwọn akẹgbẹ́ wọn.
- Nípasẹ̀ ìpolongo ẹ̀kọ́, ẹ ṣàyípadà àlàyé nípa bí a ṣe le rí i dájú pé ẹ̀tọ́ aìláṣẹ-ìfọwọ́kan-ara-ẹlòmíràn àti aàbò ara-ẹni àwọn obìnrin fẹsẹ̀ múlẹ̀. Ẹ ṣèdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn aṣòfin, àwọn oníròyìn, àwọn olùpèsè ìtọ́jú ajẹmọ́-ìṣègùn, àti àwọn adarí ẹ̀sìn. Ẹ pèsè àwọn ohun-èlò àti irinṣẹ́ láti ró àwọn obìnrin àti àwọn ọmọdébìnrin lágbára jákèjádò Nàìjíríà. Ẹ mú ìfọ̀rọ̀jomitoro-ọ̀rọ̀ gbangbalàṣá-ta tó ní ẹ̀rí lọ́kùnúnkúndùn láti yí ọ̀rọ̀ kúrò ní ti ìtìjú àti àbùkù sí ti ìrónilagbára.
- Ẹ dè kí ẹ sì ní àkọsílẹ̀ lórí ipa tòótọ́ tí àìsọ-Àdéhùn Maputo-dòfin-abẹ́lé ní lórí ìgbé-ayé àwọn obìnrin àti ọmọdébìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà, pẹ̀lú àwọn amóríbọ́ nínú oyún-ṣíṣẹ́ aláìláàbò, ìwà-ipá adálórí-lákọ-lábo àti/tàbí ìjanilógun ajẹmọ́-ìbálòpọ̀. Ẹ fi àkọsílẹ̀-ìròyìn ìkọ̀kọ̀ ránṣẹ́ nípa lílo ètò ìròyìn-ìkọ̀kọ̀ SOAWR láti mú ìjọba kó àkóyawọ́.

# Endnotes


[i] AU (2003). Protocol to the African Charter on Human and Peoples' Rights on the Rights of Women in Africa. Adopted 11 July 2003, entered into force 25 November 2005. Available at https://au.int/en/treaties/protocol-rights-women-africa

[ii] SOAWR (2023). Mapping 20 Years of Progress: Ratifying & Domesticating the Maputo Protocol. Available at https://soawr.org/resources_posts/mapping-20-years-of-progress-ratifying-domesticating-the-maputo-protocol/ [Accessed 09 April 2026]

[iii] Durojaye, E. (2023). Article 14: Health and Reproductive Rights. In A. Rudman et al. (eds). The Protocol to the African Charter on Human and Peoples' Rights on the Rights of Women in Africa: A Commentary. Pretoria: University of Pretoria Press. Available at https://www.pulp.up.ac.za/images/edocman/pulp-commentaries/protocol_to_ACHPR/Article_14.pdf

[iv] Consulate General of the Federal Republic of Nigeria (n.d.). Our Government. Available at https://nigeriaconsulatenewyork.org/about-nigeria/our-government/ [accessed 22 April 2026]

[v] UNFPA (n.d.). Nigeria Population 2025. Available at https://www.unfpa.org/data/world-population/NG [accessed 22 April 2026]

[vi] Consulate General of the Federal Republic of Nigeria (n.d.). Our Government.

[vii] Ibid.

[viii] Olomojobi, Y. and Oga, J. (2022). Nigeria: Between Monist and Dualist State. International Journal of Legal Developments and Allied Issues 8(4): 12 – 33. Available at https://www.researchgate.net/publication/364314405_NIGERIA_BETWEEN_MONIST_AND_DUALIST_STATE

[ix] Constitution of the Federal Republic of Nigeria 1999. Available at https://nigeriarights.gov.ng/files/constitution.pdf

[x] Chapter II, Section 17(3)(c). The non-justiciability of Chapter II provisions is well established; see also Olomojobi, Y. and Oga, J. (2022). Nigeria: Between Monist and Dualist State.

[xi] Criminal Code Act 2004 (applicable in southern states). Available at https://lawsofnigeria.placng.org/laws/C38.pdf; Center for Reproductive Rights. (n.d.). Nigeria's Abortion Provisions. Available at https://reproductiverights.org/maps/provision/nigerias-abortion-provisions/ [accessed 9 April 2026]; Ipas Nigeria (2020). Abortion Law and Policy in Nigeria. Available at: https://www.ipas.org/wp-content/uploads/2020/07/ALPNIGE15-AbortionLawNigeria.pdf

[xii] Penal Code Act 1960 (applicable in northern states). Available at https://lawsofnigeria.placng.org/view2.php?sn=432; Center for Reproductive Rights (n.d.). Nigeria's Abortion Provisions.

[xiii] Love Matters (n.d.). Abortion: Types and the Nigerian Law. Available at https://web.archive.org/web/20201128024619/https:/lovematters.ng/pregnancy/unsure-about-being-pregnant/abortion-types-and-nigerian-law [accessed 9 April 2026]

[xiv] Violence Against Persons (Prohibition) Act 2015. Available at http://www.refworld.org/docid/556d5eb14.html

[xv] Child Rights Act 2003. Available at https://www.refworld.org/legal/legislation/natlegbod/2003/105082

[xvi] National Health Act 2014. Available at https://scorecard.prb.org/wp-content/uploads/2019/06/Nigeria-National-Health-Act-2014.pdf; Ilesanmi, O. S., Afolabi, A. A. and Adeoya, C. T, 2023). Driving the Implementation of the National Health Act of Nigeria. Pan African Medical Journal 11(45: 147. Available at https://pmc.ncbi.nlm.nih.gov/articles/PMC10589412/

[xvii] National Health Insurance Act 2022. Available at https://www.nhia.gov.ng/wp-content/uploads/2024/03/NHIA-Act-2022-Gazetted-Copy.pdf

[xviii] National Gender Policy 2021–2026. Available at https://www.wrapanigeria.org/revised-2021-2026-national-gender-policy/

[xix] UNFPA Nigeria (n.d.). Gender-Based Violence. Available at https://nigeria.unfpa.org/en/topics/gender-based-violence-0 [accessed 9 April 2026]

[xx] Onyemelukwe, C. (2016). Legislating on Violence Against Women: A Critical Analysis of Nigeria's Recent Violence Against Persons (Prohibition) Act, 2015. DePaul Journal of Women, Gender and the Law 5. Available at https://via.library.depaul.edu/jwgl/vol5/iss2/3

[xxi] SOAWR (2023). Mapping 20 Years of Progress.

[xxii] Equality Now (2023). Regional Mapping and Assessment.

[xxiii] Okeke, T., Anyaehie, U. and Ezenyeaku, C. (2012). An Overview of Female Genital Mutilation in Nigeria. Annals of Medical and Health Sciences Research 2(1): 70–73. Available at https://doi.org/10.4103/2141-9248.96942

[xxiv] Federal Ministry of Health (2016). Promoting the Health of Nigerians to Accelerate Socio-economic Development. September. Available at https://naca.gov.ng/wp-content/uploads/2019/10/National-Health-Policy-Final-copy.pdf

[xxv] National Policy & Plan of Action for the Elimination of Female Genital Mutilation in Nigeria 2021–2025. Available at: https://nigeria.unfpa.org/en/publications/national-policy-plan-action-elimination-female-genital-mutilation-nigeria-2021-2025

[xxvi] UNICEF (2024). Nigeria Takes Bold Steps to End Child Marriage and Protect the Rights of Children. 16 February. Available at https://www.unicef.org/nigeria/press-releases/nigeria-takes-bold-steps-end-child-marriage-and-protect-rights-children

[xxvii] Equality Now (2023). Regional Mapping and Assessment.

[xxviii] Placng.org. (n.d.). What Is the Special Seats Bill? Available at https://placng.org/specialseatsbill/ [accessed 10 April 2026]

[xxix] Ibid.

[xxx] Equality Now (2023). Regional Mapping and Assessment.

[xxxi] Guttmacher Institute (2015). Abortion in Nigeria. Factsheet. New York: Guttmacher Institute. Available at https://www.guttmacher.org/fact-sheet/abortion-nigeria

[xxxii] SOAWR (2023). Mapping 20 Years of Progress.

[xxxiii] Guttmacher Institute (2015). Abortion in Nigeria. Factsheet. New York: Guttmacher Institute. Available at https://www.guttmacher.org/fact-sheet/abortion-nigeria

[xxxiv] Adejumo, O. (2024). Demystifying the Legal Restrictions on Abortion in Nigeria: Time to Change the Narrative. African Human Rights Law Journal 24(2): 559–578. Available at http://dx.doi.org/10.17159/1996-2096/2024/v24n2a7

[xxxv] Constitution of the Federal Republic of Nigeria 1999 (as amended), Section 12 (requiring legislative enactment for treaties to have force of law); see also Olomojobi, Y. and Oga, J. (2022). Nigeria: Between Monist and Dualist State.

[xxxvi] Reproductive Justice Initiative Foundation (RJIF) v Attorney General of the Federation & Others, Federal High Court, Abuja (Hon. Justice Olotu presiding), judgement delivered June 2025; Center for Reproductive Rights (2025). Victory for Women's Rights: Nigerian Federal High Court Affirms Right to Safe Abortion for Survivors of Sexual Violence. Press Release. 26 June. Available at https://reproductiverights.org/victory-womens-rights-nigerian-federal-high-court-affirms-right-safe-abortion-survivors-sexual-violence/

[xxxvii] Adejumo, O. (2024). Demystifying the Legal Restrictions on Abortion in Nigeria.

[xxxviii] Olanrewaju Oloyede, I. (2014). Theologising the Mundane, Politicising the Divine: The Cross-Currents of Law, Religion and Politics in Nigeria. African Human Rights Journal 14(1): 178–202. Available at https://www.ahrlj.up.ac.za/oloyede-i-o

[xxxvix] Durojaye, E. (2023). Article 14: Health and Reproductive Rights.

[xl] Olanrewaju Oloyede, I. (2014). Theologising the Mundane, Politicising the Divine.

[xli] Adejumo, O. (2024). Demystifying the Legal Restrictions on Abortion in Nigeria.

[xlii] CSO-ECM (n.d.). https://ecmcoalitionnigeria.org/ [accessed 9 April 2026]; case study provided by BAOBAB for Women's Human Rights on 22 May 2026.

[xliii] Solidary for African Women's Rights (2023) 20 Years of the Maputo Protocol: Where Are We Now, available at: https://soawr.org/resources_posts/20-years-of-the-maputo-protocol-where-are-we-now/, page 46.

[xliv] Oye-Adeniran, B. A., Long, C. M. and Adewole, I. F. (2004). Advocacy for Reform of the Abortion Law in Nigeria. Reproductive Health Matters 12(sup24): 209–217. Available at https://doi.org/10.1016/s0968-8080(04)24025-3

[xlv] Sendaula, B. (2023). Mapping Tool: The Regional Procedure and Fora for SRHR Litigation in Africa. Ahaki, 3 April. Available at https://www.afyanahaki.org/download/mapping-tool-the-regional-procedure-and-fora-for-srhr-litigation-in-africa/

[xlvi] Kanyali Mwikya, K., Osero-Ageng'o, C. and Waweru, E. (eds) (2020). Litigating the Maputo Protocol: A Compendium of Strategies and Approaches for Defending the Rights of Women and Girls in Africa. SOAWR and Equality Now, p. 179. Available at https://soawr.org/wp-content/uploads/Compendium_of_Papers_on_the_Maputo_Protocol_Equality_Now_2020_Final.pdf

[xlvii] Dorothy Njemanze & 3 Others v Federal Republic of Nigeria, Suit No. ECW/CCJ/APP/17/14, Judgement No. ECW/CCJ/JUD/08/17, ECOWAS Community Court of Justice, 12 October 2017.

[xlviii] SOAWR (2023). Mapping 20 Years of Progress.

[xlix] RJIF v Attorney General of the Federation & Others.

Dodoo, N.D., Moore, A.M., Nsabwe, A., and Singh, S. (2026). Abortion Care, Unsafe Abortion and Postabortion Care in Malawi. Guttmacher Institute. Available at: https://www.guttmacher.org/fact-sheet/abortion-care-unsafe-abortion-and-postabortion-care-malawi

[l] Adejumo, O. (2024). Demystifying the Legal Restrictions on Abortion in Nigeria.

MEWC
Make Every Woman Count

SOLIDARITY FOR AFRICAN WOMEN'S RIGHTS
A force for freedom

MOUVEMENT DE SOLIDARITÉ POUR LES DROITS DES FEMMES AFRICAINES
Une force pour la liberté

BAOBAB
FOR WOMEN'S HUMAN RIGHTS

AKINA MAMA WA AFRIKA